DOKITA MAJA DI OLOYE BABA EKO

# IROHIN YORUBA

Ṣẹ̀ẹ Oro Wa—"IWAJU L'OPA ẸBITI NRE SI"


**Akiyesi**

a l(ẹ) ki awọn onibara wa ma san owo ti ipe wa dede, nitori ko ba (?)a owo tita, ki o ma ya a lẹsẹ ti a ba da a duro lojiji, a o si gba owo wa lọwọ rẹ

OLOTU
IROHIN YORUBA

FARMERS' BANK FỌ : NCNC YỌ ỌLỌLA NWAPA L'EGBE


VOL. VIII NO. 389 IBADAN, MONDAY, DECEMBER 22, 1952, OWO IWE IROHIN YORUBA — KOBO KAN (1d)


## Dokita Maja Di Oloye Baba Eko

Bi ọsẹ kan sẹhin ni Dokit Akinọla Maja ti ba ọkọ ofurufu de si Kano lati India o si ṣe ibẹwo Ẹka Ẹgbẹ Ọmọ Odudewa ti o wa ni Oke Ọya kakiri, gbogbo awọn Ẹka Ẹgbẹ na ni o si gba a lọwọ tọwọ ti nwọn si ṣe iṣẹ oriṣiriṣi fun un.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni o wọ ọkọ ofurufu kuro ni Kano o si gunlẹ si Ebute Ikẹja ni deede agogo mẹwa abọ owurọ. Ẹnia ti o wa pade rẹ lo l'ẹgbẹran, Oloye, Ọlọla ati oriṣiriṣi awọn enia pataki-pataki ni ilu ati ninu Ẹgbẹ Ọmọ Odudowa, Ẹgbẹ Action Group ati oriṣiriṣi Ẹgbẹ. Mọto ayọkẹlẹ ti awọn lọ fi pade rẹ lo ni igba.

Nigbati gbogbo enia wọn lo bọ wale, nwọn kọrọ pa Iga Idunganran lọdọ Ọba Adeniji Adele Keji o si fi tiyẹtiyẹ ki i kabọ. Alufa Ẹni-Ọwọ Biṣọpu D. P. Ade Jones ni o ṣe isin idupẹ fun un ninu Iga na. Lẹhin isin na ni Ọba Adele wa ki i ni kiaun o si fi oye "Baba Eko" da a lọla fun iṣẹ rere rẹ fun ilu.

Oloye Dọkita Akinọla Maja si dupẹ lọwọ Ọba, Oloye ati gbogbo enia ti nwọn ṣe ọyẹ fun un, o si sọ irohin ajo rẹ lọ si ilu India ti o ti dun to, ati iru ajumọṣe pupọ ti yio wa laarin ilu India ati Nigeria nisisiyi gẹgẹ bi ero irin ajo na.

O si tun wa sọ bi inu on ti dun to si oye "Baba Eko" ti Ọba Eko fi on jẹ, o ni tọlẹtọlẹ ni Ọba yi ti nfẹ fi on jẹ oye, ṣugbọn on ko fẹ, nisisiyi ti gran na wa di ohun pataki ti Ọba ati gbogbo awọn Oloye tẹnu mọ pe ki on gba, on gba oye na pẹlu ọpẹ ati inudidun nitoripe ohun enia ni ohun Ọlọrun.

Awọn Ẹgbẹ Ọmọ Odudu wa (Ẹgbẹ Ọlọ) fun Oloye Dọkita Akinọla Maja ni iwe iyọsi (Address) ti o kun fun ọpọlọpọ ọrọ iwuri nipa iṣẹ rere rẹ fun idagbasoke ilu, awọn si tun fi Ẹrin ti a fi igi ṣe to a lọrẹ fun irantí abọda irin ajo rẹ lati ilu India.

Awọn ogunlọgọ enia si nia Oloye Dọkita Akinọla Maja de ile rẹ ni 2 Garber Square, awọn si tun ṣe isin Idupẹ ati adura pupọ fun un ki awọn to bẹrẹ si ṣe ete aṣeyẹ na, ninu eto aṣeyẹ yi oriṣiriṣi onjẹ ipanu ati ọti oriṣiriṣi ni o fi tẹ gbogbo enia lọrun, awọn si ṣe ariya na titi oru ọjọ na.


GREAT BARGAIN OFFER NEW "B" TWILL BAGS Size 44 x 26 1/2 inches weight two & Quarter lbs. at unbeatable price write now to
Gelliam Products 16 Waldegrave Park Twickenham England




Oloye Dọkita Akinọla Maja "Baba Eko" nsọ Irohin irin-ajo rẹ fun gbogbo enia ni Iga Idunganran

## Igbeyawo Olufisayo Miringindin

Irohin ko to afojuba ni ọjọ ile Ọlọrun na ni o kun fun awọn keṣin oṣu yi nigbati Ọgbẹni Ebenezer Oyeṣola Ṣowẹmimọ gbe Omidan Gladys Olufisayo Stanley okan ninu awọn Ọsiṣẹ Service Press Ltd., Eko ni Iyawo. Balowọ Alufa Agba Biṣọpu D. P. Ade Jones ni o ṣe eto isin igbeyawo na bẹni awọn Alufa B. Ayọrinde A. Koku ati Alufa A. Awosanya ni ile Ọlọrun ti African Salem ti ṣe olẹranlọwọ fun Alufa Agba Church Ebute-Metta ni agogo Biṣọpu Jones ni ọjọ na. Ọgbẹni Adigun ni ṣakoso o ṣe meṣwa abọ aro.



Ẹgbẹrẹcaili ni isin igbeyawo na Arungbalẹgbẹ Ọkọ Iyawo (Boni jẹ alorípa gbogbo ti ilu t'ode (Wo oju ewe keje)

## Farmers' Bank Fọ

Ni ọjọ ọlọ titi si iṣe ọjọ Kejila oṣu yi ni awọn Olotu "Nigerian Farmers and Commercial Bank Ltd." ṣe ikede pe Ile-Owo awọn ko le ṣiṣẹ mọ, nitorina o kuku dara ki awọn ti han fun gbogbo enia ti Banki awọn fọ!

Nigbati olọgo ti Olotu Banki na Ọgbẹni a S. O. Cokes ṣe ni pe awọn ni ọkọ medogbọn pọnun (£500,000) lọwọ ṣugbọn Ijọba ko fun awọn ni iwe aṣẹ (Licence) lati ma a ṣiṣẹ gẹgẹbi ofin titun ti awọn Igbimọ Aṣofin Nigeria ṣẹṣẹ ṣe lori iṣẹ Owo Banki.

Nipa bayi awọn onibara awọn ko ni gbọkanle si awọn mọ pe iṣẹ awọn le rubọ fi idi mulẹ ati pe nigbati "Standard Bank" fọ, eru ba gbogbo awọn onibara awọn, awọn si bẹrẹ si wa gba owo wọn, bẹni ṣaikẹni ko si fun wọn ni owo pamọ mọ nitoripe Banki "Standard Bank" ti ṣubu.

Lẹhin eyi awọn ṣe ikede pe Banki awọn ko le tete fọ bẹyẹ nitorina ki awọn onibara awọn ma foya, ṣugbọn nipa ọrọ agbọsọ ti nwọn nso kakiri pe "iṣẹ ni iṣẹ awọn ti fọn ọlọ" eyi mu ki awọn enibara wọn rọnti pe awọn ṣe ọlọ owo awọn ṣe a ni.

Nigbati awọn wọpe pe ti awọn ko ba tete tun irin ajo iṣẹ-ṣiṣe Banki na wa si opin awọn onibara awọn tabi awọn ti o ni owo ninu ipilẹ owo na ko ni le ri owo wọn gba pe nitorina on ko si fun Olotu Banki na mọ, on ti fi iṣẹ na le Asangbesa (Liquidator) lọwọ on ni yio mun ba ijẹ na lọ. Ṣugbọn ti o ba ni owo nibẹ ki o ma a lọ ti i igbagbọ on ni pe awọn yio tun dide.

## NCNC Yọ Nwapa Kuro l'Ẹgbẹ

JOS—Ni ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn Ipade Igbimọ Ẹgbẹ N.C.N.C ti nwọn fi Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe jẹ Olori ati Alaga pinnu ninu ipade wọn pe awọn yọ Ọlọla A. C. Nwapa (Minister of Commerce and Industries) Ọlọla Eni Njoku (Minister of Mines and Power) ati Ọlọla Okoi Arikpo (Minister of Lands & Survey) kuro ninu Ẹgbẹ N.C.N.C.

(Wo oju ewe kejila)

Irohin Yoruba

... ATI-IWAJU L'APA EBITI MKE ...
... — OLOTU IROHIN YORUBA
IYE OWO IROHIN YORUBA ODUN KAN
... —Sile merin ati hobo merin (4/4)
ILU MIRAN NI NIGERIA ATI ODE OKUN—Sile mefa hobo mefa (6/6)
IDAJI IYE OWO WON NI A NGBA FUN IDAJI ODUN

Vol. VIII IBADAN, MONDAY, DECEMBER 22, 1952 No 389

## AWOLOWO FI OLA WA HAN

O ni láti jẹ inu didún fun wa gegẹ bi orilẹ-ede Yorubá nigbati a bá ngbọ okiki ọ̀yẹ́ ti awọn ara ilẹ India ṣe fun awọn Ọlọla wa Ọbafẹmi Awolọ́wọ Alákoso Ìjọba Iwọ-orun Nigeria ati A, M. Akinloyè Alakoso Iṣẹ-àgbẹ Iwọ-orun Nigeria pẹlu awọn akọwe wọn mejeji.

Yoruba, awọn baba wa ni i ma a pa a l'owe ti nwọn si tun i ma a fi lu ilu jo pe "Bi a ba le ni, bi a ko ba ba ni iwọn ni a ba ni i ṣ'ọta mọ" owe ni ẹṣin ọrọ bi ọrọ ba sọnu owe ni a fi i wa a.

Ohun ti o mu wá pa owe yi ni pe gbara ti awọn Ẹgbẹ alatako ti gbọ pe Ọlọla Awolọwọ nlọ si India ati pe yio si jẹ alejo Ijọba India ni inu ti nbi wọn ti nwọn si ti bẹrẹ si ṣe atako pe kini wọn nwa lọ? Iyẹn ko si ninu iṣẹ Ijọba. Ṣugbọn ti o ba ṣe pe awọn ni Ijọba India pe bẹẹ ni, nwọn iba sọ pe ko si iru àwọn laiyé, nwọn a ni awọn ni ọlọgbọn Ile-Orun.

Lojù wọn ko si ẹniti o gbọn to wọn laiyé, nwọn ko si mọ pe ọgbọn ori wọn, ọgbọn kọlọkọlọ ni lọdọ wa ninu ode ilajù t'oni, ọna yiowu ki nwọn le gba, nwọn a ma a ki wa ko iwaju ni, aifori f'olori lo si nje wọn ni yi.

A ki Ọgbẹ́ni Ọbafẹmi Awolọwọ pupọ nitoripe ka rohin ẹni ko dáLi ki a ba ni bẹ ẹ, inu wa dun pe bi awọn kan tilẹ ti nrohin wa fun wọn ni India pe a rẹhin pupọ ninu aiye ilajù tẹlẹtẹlẹ ri, nisiyi o wa han si awọn ara India pe "Bi iṣu ti ntu l'oko ẹgan bẹni o ntu l'oko etilé.

Ẹnyin ọmọ Yoruba gbogbo ti o wa kakiri agbaiye ti o si nfẹ ilọsiwaju ati idominirá ilu Nigeria ki o fi ara mọ gbogbo eto awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre, ki a jumọ p'ohun pọ sọ fun awọn Ẹgbẹ alatako pe "Ada l'ẹnu t'alika, igbo l'ao fi ṣan".

Sé ẹ gbọ laipẹ yi bi awọn Ọgbẹni Awolọwọ ati Akinloye ti ṣe gba ọkan ninu awọn olori Ẹgbẹ Alatako silẹ nigbati o lugbadi ofin Ijọba Egypt ti nwọn si f'ofin de mọlẹ bi agutan. Bi o kaaraa ki nwọn dupẹ lọwọ awọn olori ẹgbẹ Afẹnifẹre wọnyi nṣe ni nwọn pa pinrin jẹ, eefin ni iwa, iwa wọn ni o fi wọn han.

A ki Ọgbẹni Ọlọla Awolọwọ ati ọgbẹni Ọlọla A. M. A. Akinloye k'abọ irin ajo wọn, ki Ọlọrun jẹki gbogbo igbokegbodo wọn ṣe gbogbo ilu Nigeria ni ire o.

E ma a polowo Ọja nyin ninu iwe

"IROHIN YORUBA",

[illegible]

## Orun Ti O Ran Yi Yio Fi O Han

L. I. Ọwọ E. A. ABODERIN, SUHUM —G.C

Ototo, iọwọ magni gba mi iiye diẹ lati sọ itan kekere yi nitoripe o mu ẹkọ dani fun ẹniti o ba ni irohunpiwada.

Ni ilu kan, ọkunrin olẹ kan wa o jẹ alaini. Nigbati o di ale ọjọ kan o wa ronu wipe kini on o ti ṣe igbesi aiye on si? O wa pinnu ni ọkan re wipe bi o ba ti di afẹmọjumọ ni on yio ti jade kuro ni ile lọ si ibiti on ba ri.

Bi ilẹ ti nmọ bọ, o ti mura, o bọ si ọna bi o ti n lọ ti o rin bi ibusọ mẹrin ni ilẹ, o pade ọkunrin Olowo arinrin ajo kan ti o ru ọpọlọpọ dukia olowo iyebiye ti o nlọ si a ni ... ilu ọkunrin alaini yi. Nwọn ki ara wọn nwọn si kọja ara wọn. Ọkunrin alaini yi wa rone wipe bi ọwọ on ba tẹ ẹru yi on yio di olowo titi ọjọ aiye on.

O si pinnu iyẹkan ara rẹ lati pa ọkunrin onisowo yi, ni o ba kọlu ọkunrin onisowo na, Nwọn wa lori ija yi titi ti fi mọ niwọn bi agogo mẹfa abọ owuro ṣugbọn ọkunrin onisowo yi ko ni olurànlọwọ.

Nigbati ọkunrin alaini yi yio fi pa a o sọ ọrọ fun un wipe "aiyesi o Orun ti o yọ yi ni yio fi ẹ han" ṣugbọn ọkunrin olẹ yi ko ka ara ọrọ yi, o pa onisowo arinrin ajo yi o si ko gbogbo awọn dukia wọnyi wa ile kalẹ jojo o di olowo, o di gbajumọ o si tun kọ ile. O gbe iyawo gẹgẹbi ti alakọwe tabi gẹgẹbi igbeyawo Alarede nitoripe oamowa ni ọkunrin olẹ yi. Nigbati nwọn ti wa ẹniti o pa ọkunrin onisowo yi titi awọn ko mọ o, gbogbo enia ni ti gbagbe rẹ, awọn ko ni ifura si ọkunrin olẹ yi pe on ... ṣe iṣẹ bi na.

Ṣugbon ni ọjọ kan bi ọkunrin yi ti ji bọ si ita lati inu iyara rẹ ni nkan bi agogo mẹfa si meje o ṣe akiyesi wipe bi orun ti ran ni ọjọ ti o npa ọkunrin onisowo yi ni orun ran ni ọjọ na. O wa b... si wo boya Orun yio sọ ọrọ na lati tu aṣiri on ṣugbọn ni iyalẹnu rẹ ko ri ki Orun sọ ọrọ kan, o wa bẹrẹ si nrin ẹrin ka gbogbo inu ilé.

Ẹrin yi pọ tobẹ ti o fi ba iyawo rẹ laiya. O ro wipe ori ọkọ on yi ni, iṣẹkẹṣẹ o pe gbogbo ara adugbo, ọkunrin yi sa ẹrin ẹrin yi fun bi wakati mẹrin. Lẹhin eyi o pe obinrin rẹ o wi fun un bi on ti ṣe pa ọkunrin onisowo ijọhini ti nwọn nwadi rẹ ati ohun ti o wi ki o to ku. Nigbati on wa ṣe akiyesi orun loni ti o jẹ ti ọjọ na ni ẹrin fi npa on pe boya orun yio sọrọ.

Kini obinrin rẹ gbọ eyi ti ni o ba bọ si ode, bi ẹnikẹni ba bi i lere ato fun un l'ti ọrọ yi fi de ọdọ ọba. Oba si ranṣẹ lati mu ọkunrin yi, ni awọn ba da ọjọ ikẹ fun u, nigba yi ni o wa ranti ọrọ ti ẹniti o pa na sọ ni ọjọ na wipe "Orun yi ni yio fi on han." Bayi ni ọkunrin yi ṣe ku iku oro, o si padanu dun aiye rẹ nipa olẹ ati ojukokoro ti o sọ ọ di apania. Ẹ jẹki a ma a ranti pe ẹnikẹni ti o ba panla p'pa ni a o pa a, ọrọ yi ni o mu Kaini ti o pa Abeli aburo rẹ di isansa ati alarinkiri ni gbogbo ọjọ aiye rẹ ki ọdẹ kan to wa pa a.



ANIYAMO EWI AS MELO

Abiko ọmọ ada ẹ l'ama bi?
Awọn arun wọnyi ha nyọ ọmọ rẹ lẹnu bi

AIPERI
OREBE
INU-IWO
OSI
IGBONA
IKO
IGBE-ORIN
OTUTU
IBA
IGBOJEDI

Iti orisiriṣi awọn arun miran ti ima yọ ọmọwẹwẹ l'ẹnu ni igba EHIN HIHU, lọ ra "YARO" awọn igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọ lẹnu.

"YARO" ni pe mẹta ni gbogbo ile Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe oruko "YARO" ni o wa lara igo na ki a ma ba ta adamodi ayederu fun ẹ.

